

# Ọjọ àkọ́kọ́ mi ninu Isilaamu

Alaye ti o rọrun fun awọn ìpìlẹ̀ mẹta ti Musulumi titun gbọdọ mọ

# Ọjọ àkọ́kọ́ mi ninu Isilaamu

**Alaye ti o rọrun fun awọn ìpìlẹ̀ mẹta ti Musulumi titun gbọdọ mọ**

مركز أصول
OsoulCenter
www.osoulcenter.com

ح جمعية الدعوة والإرشاد وتوعية الجاليات بالربوة ، ١٤٤٥ هـ

أصول ، مركز

يومي الأول في الإسلام: شرح مبسط للأصول الثلاثة التي يجب على المسلم الجديد معرفتها باللغة اليوربا. / مركز أصول - ط ١..- الرياض ، ١٤٤٥ هـ

٤٨ ص ؛ ١٤.٨ x ٢١ سم

رقم الإيداع: ١٤٤٥/٢٠٥٩٨

ردمك: ٩٧٨-٦٠٣-٨٤٣٨-٢٦-٨

مركز أصول
Osoul Center
www.osoulcenter.com

- Markaz ni o pese ti o si ṣe iṣẹ́ ọnà atẹjade yii.
- Markaz yọnda títẹ atẹjade naa jáde pẹ̀lú èyíkéyìí ọ̀nà pẹlu itọka si orísun naa, lai yí nǹkan kan padà nínú ọ̀rọ̀ naa.
- Ti a ba fẹ ṣe atẹjade naa, o di dandan ki a tẹle àwọn ìlànà dídára ti Markaz Usuul fi ọwọ́ si.

بسم الله الرحمن الرحيم

**Pẹlu orukọ Ọlọhun Ọba**
**Ajọkẹ ayé Àṣàkẹ́ ọrun**



Ìpìlẹ̀ Àkọ́kọ́
Ta ni Oluwa rẹ? 13

Ipilẹ keji
Ki ni ẹsin rẹ 21

Ipilẹ kẹta
Ta ni Anabi rẹ 37



# Abawọle

# Isilaamu
## ni ẹsin ododo

Ẹsin Isilaamu, oun ni ẹsin ododo ti Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- yọnu si i fun gbogbo eniyan patapata, oun ni ẹsin ti wọn ko nii gba eyi ti o yatọ si i lọdọ Ọlọhun, Ọba ti ọla Rẹ ga n sọ pe: {Dájúdájú ẹ̀sìn t'ó wà lọ́dọ̀ Allāhu ni 'Islām} [Surah Âl-`Imrân: 19] Ọba ti O gbọnngbọn ti O ga n sọ pe: {Ẹnikẹ́ni tí ó bá wá ẹ̀sìn kan ṣe yàtọ̀ sí 'Islām, A ò níí gbà á lọ́wọ́ rẹ̀. Ní Ọjọ́ Ìkẹ́yìn, ó sì máa wà nínú àwọn ẹni òfò} Aal-Imraan 85

Ẹni ti o ba gba ẹsin Isilaamu ti o si dirọ mọ ọn, dajudaju o n rin ni oju-ọna imọlẹ ati imọna; ọna taara ti o fi oju han ti o maa muni de ọdọ Ọlọhun ti O da eniyan ti o si mu u bẹ ni aye yii.

Ẹsin Isilaamu wa pẹlu dídára iṣesi eniyan ati ifọkanbalẹ rẹ ati ìdùnnú rẹ ni isẹmi aye rẹ, ati ìdùnnú rẹ bákannáà ati ere rẹ ni isẹmi ọjọ́ ikẹyin rẹ lẹyin to ba ku, nigba ti Ọlọhun -ti ọla Rẹ ga- ba mu u wọ alujanna ti o maa gbadun pẹlu nnkan to wa nibẹ ninu idẹra gbere.

O wa jẹ dandan fun gbogbo eniyan lati ṣe ìwádìí nipa ẹsin ododo tii ṣe Isilaamu, ki o si mọ ọn, ki o si wọnu ẹ ni olugbagbọ si i, ki o si maa tẹle awọn ẹkọ ẹ ati awọn idajọ ẹ, ki ọwọ ẹ le tẹ daadaa aye ati ọrun.

# Bawo ni eniyan ṣe maa n wọ inu Isilaamu?

Èèyàn maa n wọnu Isilaamu ti o ba sọ pe: (Ash-adu an laa ilaaha illallahu wa anna Muhammadan rosuulullahi), pẹlu ododo ati amọdaju ati imọ pẹlu nnkan to da le lori, ẹni ti o ba sọ gbolohun yii ni ẹni ti o mọ itumọ ẹ ti o n sọ o pẹlu òdodo ni ẹni tí ó ni amọdaju ti o si n tẹle ohun ti o da le lori, o ti wọ inu Isilaamu, lẹyin naa o jẹ dandan fun un lati kọ awọn iṣẹ Isilaamu yoku, yio si maa ṣiṣẹ pẹlu ẹ lori bi ikapa rẹ ba ṣe to, gbogbo igba ti imọ rẹ ba ti n lekun ni igbagbọ rẹ a maa lekun ti ẹsan rẹ a si tobi lọdọ Ọlọhun -ti ọla Rẹ ga-



## Itumọ ijẹrii mejeeji ni (Mo n jẹrii pe ko si ọlọhun ti ijọsin tọ si afi Allahu ati pe dajudaju Muhammad ojiṣẹ Allāhu ni):

O ti wọnu Isilaamu pẹlu ọrọ rẹ pe: (Ash-adu an laa ilaaha illallahu wa anna Muhammadan rosuulullahi), ni ẹni ti o ni igbagbọ pẹlu ẹ to si n gba a lododo, njẹ o mọ paapaa itumọ ẹ?

- Itumọ jijẹrii pe ko si ọlọhun ti ijọsin tọ si afi Allahu ni: Oun ni nini adisọkan ati gbigba pe dajudaju pe ko si ọlọhun kankan to n bẹ ti o tọ si ijọsin ati itẹle afi Ọlọhun kan, Oun ni Allahu -mimọ ni fun Un ti ọla Rẹ ga-, Aṣẹda aye ati Oludari alamọri ẹ.



- Ati pe itumọ jijẹrii pe dajudaju Muhammad ojiṣẹ Ọlọhun ni: Oun ni nini adisọkan ati gbigba pe dajudaju Muhammad ẹru Ọlọhun ni ati ojiṣẹ Rẹ ikẹyin, ti a ran si eniyan patapata, ati ṣiṣe iṣẹ pẹlu nnkan ti iyẹn n beere fun; pẹlu itẹle rẹ nibi nnkan to ba pa laṣẹ, ati gbigba a gbọ lododo nibi nnkan to ba sọ, ati jijina si nnkan to kọ kuro nibẹ, ati pe a ko gbọdọ jọsin fun Ọlọhun afi pẹlu nnkan ti O ba ṣe lofin.

## O ku oriire pẹlu gbigba Isilaamu:

Irẹ ọmọ iya mi ọwọn, dajudaju ọjọ wiwọ inu Isilaamu rẹ ni eyi to daa julọ ninu awọn ọjọ aye rẹ, o fi ẹsẹ rinlẹ pe dajudaju Anabi wa Muhammad- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe: "Isilaamu maa n wó nnkan to ṣíwájú ẹ". Muslim ni o gba a wa. Ìtumọ̀ rẹ ni pe: Isilaamu maa n pa gbogbo nnkan to ba ṣẹlẹ lati ọdọ rẹ ṣíwájú gbigba Isilaamu rẹ, bíi aigbagbọ ati awọn aburu ati awọn aṣiṣe ati awọn ẹṣẹ, nitori naa, dunnu pẹlu aforijin Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga-, ni oni, o ti di ẹni ti a fọ mọ kuro nibi awọn aṣiṣe rẹ, ki o ṣi oju-iwe funfun ninu igbesi aye rẹ, ki o le ṣẹri pada ni ẹni mimọ bii ọjọ ti iya rẹ bi ọ, ki o si bẹrẹ igbesi aye tuntun to kun fun dáadáa, ki o si maa rin ninu oju-ọna imọlẹ ati oriire ati idunnu.

## Idunnu pẹlu idẹra Isilaamu:

Dajudaju idunnu nla ti o ni imọlara rẹ nigba ti o wọnú Isilaamu, o jẹ dandan ki o maa wa pẹlu ẹ fun gbogbo igbesi aye rẹ, idẹra imọna wa ninu eyi to gbọnngbọn julọ ninu awọn idẹra ti Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- maa n ṣe fun awọn ẹru Rẹ, o tobi ju idẹra atẹgun lọ ati omi ati ounjẹ ati nǹkan mímu, o tobi ju owo lọ ati ipo ati iyi, o ju gbogbo idẹra lọ, bawo ni a ko ṣe nii dunnu pẹlu ẹ?! Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- n sọ pe: {Sọ pé: Pẹ̀lú àjùlọ oore Allāhu (ìyẹn, al-Kur'ān) àti àánú Rẹ̀ (ìyẹn, 'Islām), nítorí ìyẹn ni kí wọ́n máa fi dunnú; ó sì lóore jùlọ sí ohun tí àwọn (aláìgbàgbọ́) ń kó jọ (nínú oore ayé).}. [Yunus: 59].

O gbọdọ maa ni imọlara ọla Ọlọhun lori rẹ látàrí pe O sa ẹ lẹsa laarin ọkẹ àìmọye ẹda lati wọ inu Isilaamu, Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: {Ẹnikẹ́ni tí Allāhu bá fẹ́ fọ̀nà mọ̀, Ó máa ṣí igbá-àyà rẹ̀ payá fún 'Islām} [Al-An'am: 125]. Idẹra nla to tobi yii n bukaata si ọpẹ to pọ, o jẹ dandan fun ẹ lati pọ ni idupẹ fun Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- ati lati maa ṣe iyin fun Un- Alagbara ti O gbọnngbọn- nitori pe O fọna mọ ẹ si ẹsin to ni alaafia.

## Awọn ipilẹ ti ko si ibuyẹ lati ma mọ wọn:

Ti o ba wọnu Isilaamu, awọn ipilẹ kan n bẹ ti kikọ rẹ ati nini imọ nipa ẹ jẹ dandan fun ẹ, ninu iyẹn ni mimọ idahun awọn ibeere mẹta to ṣe pataki to ṣe pe wọn maa bi gbogbo eniyan lẹyin iku, to si ṣe pe oun ni yoo sọ bi ìkángun gbere rẹ ṣe maa ri; boya lọ si inu alujanna ni tabi lọ si inu ina, awọn naa ni:

**Ta ni Olúwa rẹ ?**

**Ki ni ẹsin rẹ ?**

**Ta ni Anọbi rẹ ?**



Ìpìlẹ̀ Àkọ́kọ́

# Ta ni Oluwa rẹ?

## Allāhu ni Oluwa mi

Musulumi maa ni adisọkan pe Olúwa oun ni Ọlọhun ti O da ayé pẹ̀lú gbogbo nǹkan ti o wa ninu ẹ, O si da ọmọniyan

Ti a ba ronu nipa aye ńlá yii ati nǹkan ti o wa ninu rẹ, bii àwọn irawọ ńlá pẹ̀lú nǹkan ti wọn ko sínú bii àìmọye àwọn irawọ kéékèèké, ti a ba wa woye si ilẹ ti a n ṣẹmi lori rẹ yii, ati ohun ti o wa ninu ẹ bii àwọn pẹtẹlẹ ati awọn òkè, ati bii ilẹ̀ gbígbẹ ati awọn odò, ati awọn ẹ̀dá ìyanu ti wọn wa ni isalẹ-salẹ odò, ati ni pápá, ati ni aginjù, ti a ba tun woye si eemọ dida ọmọniyan, ati awọn ẹ̀dá ti wọn yatọ si wọn, dájúdájú ìrònú wa maa sun wa de ibi àbájáde kan ti ko nii ibuyẹ; oun naa ni pe Aṣẹda Ńlá kan n bẹ ti O tobi, ti O ni imọ, ti O ni ikapa, ti O si ni ọgbọ́n, Oun ni O da aye yii ti O si da a daadaa. Ko rọrùn ki a ri awọn ẹ̀dá yii láìsí Aṣẹda ti O da wọn, ti O si ṣe e ni nǹkan ti o ni ètò, ti O si da a ni ọna ti o rẹwa ti o n yani lẹnu, Ọlọhun si ti ṣàlàyé ọrọ yii dáadáa fun gbogbo oni làákàyè nígbà tí Ó sọ pe: Tàbí wọ́n ṣẹ̀dá wọn láì sí Aṣẹ̀dá? Tàbí àwọn ni wọ́n ṣẹ̀dá ara wọn ni? [Al-Tur: 35]. Àwọn ẹ̀dá yii ko maa bẹ funra wọn, wọn ko si maa bẹ lai si ẹni ti n mu wọn maa bẹ, eleyii ko rọrùn lọ́dọ̀ àwọn oni làákàyè

## Ọlọhun nìkan ni O ni ẹtọ si ìjọsìn

Oluwa yii nìkan ni O ni ẹtọ si ìjọsìn; torí pé Oun ni Aṣẹda, Oluṣeto gbogbo nǹkan ti n bẹ nínú ayé yii, Olùpèsè fun gbogbo ẹni ti n bẹ nínú ẹ, Oun ni O da gbogbo eeyan si orilẹ yii ti O si fun wọn ni àwọn àtẹ̀gùn iṣẹmi, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga n sọ pé: Ìyẹn ni Allāhu, Olúwa yín; kò sí ọlọ́hun kan tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun, Ẹlẹ́dàá gbogbo n̄ǹkan. Nítorí náà, ẹ jọ́sìn fún Un. Òun sì ni Olùṣọ́ lórí gbogbo n̄ǹkan. Suratul An'am: 102 O jẹ dandan fun eeyan kọọkan lati sin Ọlọhun nìkan, ki o si ma mu orogun nibi ìjọsìn rẹ, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Ẹ̀yin ènìyàn, ẹ jọ́sìn fún Olúwa yín, Ẹni tí Ó da ẹ̀yin àti àwọn t'ó ṣíwájú yín, nítorí kí ẹ lè ṣọ́ra (fún ìyà Iná). Suratul Baqara: 21 Ọlọhun- mímọ́ Rẹ- tun sọ pé: Ẹ jọ́sìn fún Allāhu, ẹ má ṣe fi n̄ǹkan kan ṣẹbọ sí I. An-Nisaa: 36



## Ipepe awọn Anọbi lọ síbi imu Ọlọhun lọkan

Tòun ti bi àlámọ̀rí yii ṣe hàn tó, Ọlọhun- nínú aanu ati ikẹ Rẹ- ko fi wa silẹ ki a maa ṣe bi o ṣe wu wa ninu iṣẹmi, ṣùgbọ́n O ran àwọn ojiṣẹ kan si wa, O si sọ àwọn tira kan kalẹ pẹ̀lú wọn ti wọn maa fi júwe Rẹ fun wa, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Dájúdájú Àwa fi òdodo rán ọ níṣẹ́. (O sì jẹ́) oníròó-ìdùnnú àti olùkìlọ̀. Kò sí ìjọ kan (ṣíwájú rẹ) àfi kí olùkìlọ̀ ti rè kọjá láàárin wọn. Fatir:24 Baba àwọn abara ni Adam- ki ọla Ọlọhun maa ba a- ati gbogbo awọn anọbi pata, ninu wọn ni Nuuh ati Ibrahim ati Musa ati Isa, ati awọn mìíràn nínú àwọn anọbi, de orí anọbi wa Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a-, gbogbo wọn ni wọ́n fi ẹnu ko lori ìpìlẹ̀ ńlá kan ti o tobi, oun naa ni pipe àwọn eeyan lọ sibi ini ìgbàgbọ́ si Ọlọhun ati jijọsin fun Un ni Oun nìkan, ati gbígbé ìjọsìn fun ẹlòmíràn sílẹ̀ ninu awọn ẹ̀dá abara, ati okuta, ati igi, ati awọn irawọ, ati bẹẹ bẹẹ lọ. Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe: Dájúdájú A ti gbé Òjíṣẹ́ dìde nínú ìjọ kọ̀ọ̀kan (láti jíṣẹ́) pé: Ẹ jọ́sìn fún Allāhu. Kí ẹ sì jìnnà sí àwọn òrìṣà. [An-Nahl: 36] Ọba ti O gbọnngbọn ti O ga n sọ pe: A kò rán òjíṣẹ́ kan níṣẹ́ ṣíwájú rẹ àfi kí A fi ìmísí ránṣẹ́ sí i pé: Dájúdájú kò sí ọlọ́hun tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Èmi (Allāhu). Nítorí náà, ẹ jọ́sìn fún Mi. Suratul Anbiyaa: 25



## Ninu awọn orukọ Ọlọhun ati awọn iroyin Rẹ:

Awọn orukọ to dara julọ ati awọn iroyin to ga julọ n bẹ fun Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- igba ti a ba mọ wọn, a maa lekun ni imọ nipa Olúwa wa- mimọ ni fun Un ti ọla Rẹ ga-, a si maa lekun ni ifẹ Rẹ, ati ni ipaya Rẹ, ati ni agbiyele ọla Rẹ ati ọrẹ Rẹ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- n sọ pe: Allāhu, kò sí ọlọ́hun tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun. TiRẹ̀ ni àwọn orúkọ t'ó dára jùlọ. [Taha: 8].

Awọn orukọ Rẹ to n tọka si awọn iroyin Rẹ pọ, ninu awọn orukọ Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- ni:

- **Ar-Rahman ati Ar-Roheem:** Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe: Ọlọ́hun yín, Ọlọ́hun Ọ̀kan ṣoṣo ni. Kò sí ọlọ́hun kan tí ìjọ́sìn tọ́ sí àyàfi Òun, Àjọké-ayé, Àṣàkẹ́-ọ̀run. Baqara 163 Oun ni Onikẹẹ to gbooro to tobi to gbaaye ju gbogbo nnkan lọ, ti o sì kari gbogbo ẹda, ikẹ Rẹ ni aye ko gbogbo ẹda Rẹ sinu, ninu ẹranko ati eniyan to jẹ musulumi ati awọn to yatọ si musulumi, Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: {Àti pé ìkẹ́ Mi gbòòrò ju gbogbo ǹǹkan lọ} [Al-A'araf: 156]. Oun ni O n pese ijẹ-imu fun wọn patapata ti O n fun wọn ni alaafia ati ounjẹ ati awọn ọmọ ati eyi to yatọ si yẹn, sugbọn ikẹ Rẹ ni ọjọ ikẹyin ko nii jẹ ti ẹnikẹni afi awọn olugbagbọ ododo ninu awọn ẹru Rẹ, ati awọn olutẹle awọn Anabi Rẹ ati awọn ojiṣẹ Rẹ, awọn wọnyi ni ikẹ to pe ti o n múni de ibi oriire gbere maa bẹ fun wọn.

- **Ẹlẹdaa:** Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: {Allāhu ni Ẹlẹ́dàá gbogbo ǹǹkan} [Surah Az-Zumar: 62] Oun ni O da awọn sanmọ ati ilẹ ati nnkan to n bẹ laarin mejeeji, ati pe O da gbogbo nnkan lati ori nnkan to kere bíi ọmọ ina-igun titi dórí irawọ, ati nǹkan ti o gbòòrò ju ìyẹn lọ, O tun da a bákannáà pẹlu ọgbọn Rẹ, ati agbara Rẹ, ati daadaa, o o nii ri adinkun tabi aayẹ nibi ẹda Rẹ.

- **Alaforijin:** Ẹni ti O maa n ṣe aforijin awọn ẹṣẹ patapata fun ẹni ti o ba ronupiwada looọtọ, gbogbo ohun ti o ba ri ki o ti ṣe ṣíwájú, bi ko ṣe pe o maa n ṣe amojukuro fun ọpọlọpọ ninu ẹda Rẹ ni ti ọrẹ lati ọdọ Rẹ- yatọ si ẹbọ nibi ijọsin Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga-, dajudaju ko nii ṣe aforijin afi pẹlu ironupiwada, ati pe Ọlọhun ti ṣi awọn okùnfà silẹ fun gbogbo ẹda Rẹ lati ri aforijin Rẹ; pẹlu ironupiwada, ati iwaforijin, ati igbagbọ, ati iṣẹ rere, ati iwa dáadáa si ẹda Ọlọhun, Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pẹ: {Dájúdájú Èmi ni Aláforíjìn fún ẹnikẹ́ni tí ó bá ronú pìwàdà, tí ó gbàgbọ́ ní òdodo, tí ó sì ṣe iṣẹ́ rere, lẹ́yìn náà tí ó tún tẹ̀lé ìmọ̀nà}. [Taha: 82].

- **Olupese:** Ọlọhun- mimọ ni fun Un- ni Olukapa ti ijọba gbogbo nnkan wa ni ọwọ Rẹ, Oun ni Ọlọrọ, ninu ọla Rẹ ni pe Ọlọrẹ ni, ko si ẹda kan afi ki arisiki rẹ wa lọdọ Ọlọhun, Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: {Àti pé Èmi kò ṣẹ̀dá àlùjànnú àti ènìyàn bí kò ṣe pé kí wọ́n lè jọ́sìn fún Mi * Èmi kò gbèrò arísìkí kan láti ọ̀dọ̀ wọn. Èmi kò sì gbèrò pé kí wọ́n máa bọ́ Mi * Dájúdájú Allāhu, Òun ni Olùpèsè, Alágbára líle}." Sūratudh Dhāriyāt: 56-58.

- **Alailabuku:** Ẹni ti a n gbe tobi ti a n fọ mọ kuro nibi awọn aleebu ati kuro nibi awọn iroyin adinku patapata, Ẹni to ṣe pe àwọn iroyin pipe ati gbigbọnngbọn ati ẹwa n bẹ fun, Ẹni to ṣe pe O nífẹ̀ẹ́ fifọn alaafia ka laarin awọn ẹru Rẹ pẹlu ọrọ ati iṣẹ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- n sọ pe: {Òun ni Allāhu, kò sí ọlọ́hun tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun. Ọba (ẹ̀dá), Ẹni-mímọ́ jùlọ, Aláìlábùkù } [Al-Hashr: 23].



- **Onimọ julọ:** Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- ni Olugbọ Oluriran Onimọ julọ, ti imọ rẹ rọkirika gbogbo nnkan, O ni imọ nipa nnkan to n bẹ ni gbanngba, ati nnkan to n bẹ ni kọkọ, ati nnkan ti igba-aya n gbe pamọ, O mọ nnkan to bẹ ni igba to ti lọ, ati nnkan to n bẹ lọwọ lọwọ, ati nnkan ti o maa bẹ ni ọjọ-iwaju, Oun ni Oluṣọ to ṣe pe O n ri awọn iṣẹ awọn ẹru, itẹle awọn olutẹle ko pamọ fun Un tabi iyapa awọn oluyapa, tabi ini bukaata awọn ọlẹ tabi ohun awọn olupepe, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe: {dájúdáju Allāhu ni Onímọ̀ nípa gbogbo ñǹkan} [Al-Baqarah: 231]

Oun- mimọ ni fun Un- ni Oluwa àwọn ẹ̀dá, Ẹni to ṣe pe O ṣe gbogbo nnkan to da ni dáadáa, gbogbo dáadáa ati pipe to n bẹ ni aye yii, o wa ninu awọn oripa pipe Rẹ- mimọ ni fun Un-





Ipilẹ keji

# Ki ni ẹsin rẹ?

## Ẹsin mi ni ẹsin Isilaamu:

Ati pe Isilaamu: Oun ni ijupa-jusẹ silẹ fun Ọlọhun pẹlu igbagbọ ninu Oun nikan ṣoṣo, ati itẹle E pẹlu itẹle aṣẹ Rẹ, ati bibọpa-bọsẹ kuro nibi ẹbọ.

- Musulumi ni ẹni ti o n wọnu ẹsin Isilaamu, ti o si fa alamọri rẹ le Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- lọ́wọ́ lẹniti o ni igbagbọ ninu bibẹ Rẹ ati ijẹ-ọkan-ṣoṣo Rẹ, ti o n tẹle awọn aṣẹ Rẹ, ti o n jina si awọn nnkan t'O ba kọ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- n sọ ninu Kuraani Alapọn-ọnle pe: {Ta l'ó dára ní ẹ̀sìn ju ẹni tí ó jura rẹ̀ sílẹ̀ fún Allāhu, olùṣe-rere sì tún ni, ó tún tẹ̀lé ẹ̀sìn (Ànábì) 'Ibrọ̄hīm, olùdúró-déédé-nínú-'Islām?} Suratu Nisai: 125 "O tun sọ pe: " "Ta ni ó dára jùlọ ní ọ̀rọ̀ sísọ t'ó tayọ ẹni tí ó pèpè sí ọ̀dọ̀ Allāhu, tí ó ṣe iṣẹ́ rere, tí ó sì sọ pé: "Dájúdájú èmi wà nínú àwọn mùsùlùmí." (Fussilat:33)



## Ninu awọn dáadáa ẹsin Isilaamu ni:

- Isilaamu ni ẹsin deedee: O n paṣẹ ṣiṣe deedee pẹlu ẹni tí ó sunmọ ati ẹni ti o jina, ati ọta ati ọrẹ, ati olugbagbọ ati alaigbagbọ, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- n sọ pe: {Dájúdájú Allāhu ń pàṣẹ ṣíṣe déédé} An-Nah'l 90 Ọlọhun- Alagbara ti O gbọnngbọn- Ọba Adajọ Oluṣe deedee ti wọn ko le ṣe abosi ẹnikẹni lọdọ Rẹ ni, Ọba ti ọla Rẹ ga n sọ nipa ọjọ igbedide pe: {Ní òní ni A óò san ẹ̀mí kọ̀ọ̀kan ní ẹ̀san ohun tí ó ṣe níṣẹ́. Kò sì sí àbòsí kan ní òní} Suuratu Gaafir: 17.

- Isilaamu ẹsin ikẹ ni: Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- n sọ pẹ: A kò sì fi iṣẹ́ ìmísí rán ọ bí kò ṣe pé kí o lè jẹ́ ìkẹ́ fún gbogbo ẹ̀dá. Suuratul Anbiyaah: 107. Anabi Muhammad -ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pe: " Àwọn onikẹẹ, Ọba Ajọke-aye a maa kẹ wọn, ẹ maa ṣe ikẹ awọn ara ilẹ, Ẹni ti O wa ni sanmọ a maa kẹ yin". Abu Daud ni o gba a wa.

- Isilaamu ẹsin ifẹ ati akojọ ati isopọ ni: Anabi Muhammad- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- n sọ pe: "Ẹnikẹni ninu yin o le tii di olugbagbọ, titi yóò fi fẹ fun ọmọ-iya rẹ nnkan to fẹ fun ara rẹ" Bukhari ni o gba a wa.



- Isilaamu ẹsin irọrun ni: Nitori naa, irọrun ati gbigbe wahala kuro n bẹ nínú awọn ẹkọ Isilaamu ti gbogbo ẹni ti o ba mọ awọn ẹkọ ẹ maa mọ ọn, Ọba ti ọla Rẹ ga n sọ pe: {Allāhu fẹ́ ìrọ̀rùn fun yín, kò sì fẹ́ ìnira fun yín} [Surah Al-Baqarah: 185] O tun sọ pe: {Allāhu kò fẹ́ láti kó wàhálà ba yín}. Suratul-Maa'idah ayah 6 O tun n sọ pe: "{Allāhu kò làbọ ẹ̀mí kan lọ́rùn àfi ìwọ̀n agbára rẹ̀}." [Al-Baqarah: 286].

- Isilaamu ẹsin imọ ni: Nitori naa aayah akọkọ to sọkalẹ ninu Kuraani ni: {Ké (al-Ḱur'ān) pẹ̀lú orúkọ Olúwa rẹ, Ẹni tí Ó dá ẹ̀dá} [Al-Alaq: 1]. Isilaamu maa n ṣe gbogbo musulumi lọkunrin ati lobinrin lojukokoro lori wiwa imọ ati wiwa alekun ninu imọ, Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Kí o sì sọ pé: Olúwa mi, ṣàlékún ìmọ̀ fún mi. Too'haa: 114 Ipo to ga julọ nbẹ fun akẹkọọ, Ọba ti mimọ n bẹ fun Un ti ọla Rẹ ga n sọ pe: {Allāhu yóò ṣàgbéga àwọn ipò fún àwọn t'ó gbàgbọ́ ní òdodo àti àwọn tí A fún ní ìmọ̀ nínú yín} (Suratul Mujaadalah: 11)

## Kikari ayé ẹsin Isilaamu:

- Isilaamu jẹ ẹsin agbaye, ko ki n ṣe fun ààyè kan pàtó lórí ilẹ̀ ti ko si fun aaye miiran, ko si si fun ijọ kan pàtó yatọ si ijọ miiran, kii sii ṣe ẹsin fun iran larubawa nikan, bi ko ṣe pe ẹsin kan ni fun gbogbo eniyan, Ọba ti ọla Rẹ ga sọ ni Ẹni ti O n ba Anabi Rẹ Muhammad- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọrọ ninu Kuraani Alapọn-ọnle pe: {Sọ pé: Ẹ̀yin ènìyàn, dájúdájú èmi ni Òjíṣẹ́ Allāhu sí gbogbo yín pátápátá. (Allāhu) Ẹni t'Ó ni ìjọba àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀. Kò sí ọlọ́hun tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Òun. Ó ń sọ ẹ̀dá di alàààyè. Ó sì ń sọ ẹ̀dá di òkú. Nítorí náà, ẹ gbàgbọ́ nínú Allāhu àti Òjíṣẹ́ Rẹ̀. Ànábì aláìmọ̀ọ́nkọmọ̀ọ́nkà, ẹni t'ó gbàgbọ́ nínú Allāhu àti àwọn ọ̀rọ̀ Rẹ̀. Ẹ tẹ̀lé e nítorí kí ẹ lè mọ̀nà} Suratul A'raf: 158

- Gẹgẹ bi o ṣe jẹ pe ko ki n ṣe fun asiko kan pato to ti lọ, bi ko ṣe pe oun ni ẹsin ododo lati igba ti wọn ti gbe Anabi Muhammad- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- dide, titi di ọjọ igbedide, Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Ẹnikẹ́ni tí ó bá wá ẹ̀sìn kan ṣe yàtọ̀ sí 'Islām, A ò níí gbà á lọ́wọ́ rẹ̀. Ní Ọjọ́ Ìkẹ́yìn, ó sì máa wà nínú àwọn ẹni òfò. Aal-Imraan 85

## Gbígbòòrò ẹsin Isilaamu

- Isilaamu, ìlànà igbesi aye ni; fun musulumi kọọkan, ati fun awujọ musulumi, ati fun ìjọ musulumi, ni gbogbo awọn abala ati aaye; nibi ọrọ oṣelu ati ọrọ-aje ati àwùjọ ati eyi to yatọ si i.

- Isilaamu adisọkan ati ofin ni: Oun ni ẹsin ti o ko awọn adisọkan to ni alaafia sínú, ati awọn ijọsin ti o tobi, ati awọn ibaṣepọ ti o kun fun ọgbọn, ati awọn iwa to rẹwa, ati ihuwasi to duro déédéé.

- Awọn ẹkọ Isilaamu ati awọn idajọ rẹ maa n ṣe àkóso asopọ eniyan papọ mọ Oluwa rẹ, ati asopọ eniyan pẹlu ara rẹ, ati asopọ eniyan pẹlu ẹlomiran ninu eniyan, titi dori asopọ rẹ pẹlu awọn ẹranko ati nnkan ọbọrọgidi

- Awọn ẹkọ Isilaamu ko nnkan to sopọ mọ dídára ẹmi ati ara sinu.

**Ni akotan: Isilaamu wa pẹlu nnkan ti oore àwọn èèyàn ati dídára wọn ati oriire wọn ni aye ati ọjọ ikẹyin n bẹ nibẹ.**

# Awọn ipilẹ adisọkan ti Isilaamu

## Awọn origun igbagbọ

Awọn ipilẹ adisọkan ti Isilaamu n fara hàn nínú igbagbọ ati igbalododo to rinlẹ si awọn nnkan mẹfa kan ti wọn n pe wọn ni (Awọn origun igbagbọ), awọn ni:

**1- Nini igbagbọ ninu Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga-:** Ìtumọ̀ rẹ ni nini igbagbọ ninu bibẹ Ọlọhun, ati pe dajudaju Oun nikan ni Aṣẹda ati Olukapa ati Oluṣeto aye patapata pẹlu nnkan to wa nibẹ, ati pe Oun Ẹni ti O tọ si ijọsin l'Oun nikan ṣoṣo ti ko si orogun fun Un, ati pe Oun ni ẹni ti a n royin pẹlu iroyin to rẹwa ti o gbọnngbọn, ati pe Oun ni Ọba ti O pe ti O mọ kuro nibi gbogbo aleebu ati adinku, ati pe ko si nnkan to da bii Rẹ.



**2- Nini igbagbọ ninu awọn mọlaika:** Awọn ni ẹda kan ninu ẹda Ọlọhun -ti ọla Rẹ ga- ti O da wọn fun ijọsin Rẹ, ati itẹle to pe fun àṣẹ Rẹ, ati ṣíṣe àwọn nnkan ti wọn fi wọn ṣe amujuto rẹ ninu awọn iṣẹ, nitori naa, a maa ni igbagbọ ninu bibẹ wọn lapapọ, gẹgẹ bi a ṣe maa ni igbagbọ ninu awọn orukọ Rẹ ati awọn iroyin Rẹ ati iṣẹ àwọn ti imisi fun wa ni iro nípa wọn ni ifọsiwẹwẹ; gẹgẹ bii Jibril ti Ọlọhun maa n ran pẹlu imisi si awọn Anabi ati awọn Ojiṣẹ, ati Mikail ti a fi ṣe alamojuto ojo ati awọn irugbin, ati Israfil ti a fi ṣe alamojuto fifọn fere, ati mọlaika ikú ti o n gba ẹmi àwọn eniyan, ati Maalik tii ṣe ẹ̀ṣọ́ ina.

**3- Nini igbagbọ ninu awọn iwe:** Awọn ni awọn iwe ti Ọlọhun sọ wọn kalẹ fun awọn Ojiṣẹ Rẹ, lati jẹ ikẹ fun ẹda, ati lati jẹ imọna fun wọn; ki wọn le de ibi oriire aye ati ọjọ ikẹyin, nitori naa, a maa ni igbagbọ ninu wọn lapapọ, a maa ni igbagbọ si eyi ti a ni imọ nipa orúkọ rẹ ninu wọn pẹlu imisi ni ifọsiwẹwẹ; gẹgẹ bii Kuraani ti wọn sọkalẹ fun Muhammad- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a-, ati Injeel ti wọn sọkalẹ fun Isa- ki ikẹ Ọlọhun maa ba a- ati Taorat ti wọn sọkalẹ fun Musa- ki ikẹ Ọlọhun maa ba a-, ati Zabur ti wọn fun Daud- ki ikẹ Ọlọhun maa ba a-, ati Suhuf ti Ọlọhun sọkalẹ fun Ibrahim- ki ikẹ Ọlọhun maa ba a-.

**4- Nini igbagbọ si awọn Ojiṣẹ:** Awọn ni ẹda kan ti Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- mi awọn imọna si wọn, ti O ran wọn si eniyan ki wọn le mu ẹsin rẹ de ogongo, àkọ́kọ́ ninu wọn ni Nuuh- ki ikẹ Ọlọhun maa ba a-, ti ikẹyin wọn jẹ Muhammad- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a-, wọn jẹ ẹni to pe ni ẹsin ati iwa, eyi to ṣe pataki julọ ninu erongba ninu igbedide wọn ni pipe àwọn eniyan lọ si imu Ọlọhun- mimọ ni fun Un ti ọla Rẹ ga- lọkan ṣoṣo pẹlu ijọsin, ati lati gbe ẹbọ ju silẹ ati ijọsin ẹni ti o yatọ si I, ati lati jẹ ki wọn maa ṣe ohun rere, ati lati jẹ ki wọn gbe aburu ju silẹ.

A maa ni igbagbọ pe dajudaju Ọlọhun ran awọn Ojiṣẹ kan ninu eniyan, ti O ṣe gbigba wọn lododo ni ọranyan lori awọn ẹru nibi nnkan ti wọn sọ ati titẹle àṣẹ wọn ati titẹle nnkan ti wọn ba pa laṣẹ, ati pe ki a mọ pe dajudaju o n bẹ ninu wọn awọn ti Ọlọhun fun wa ni iro nipa wọn orukọ wọn ati awọn itan wọn pẹlu awọn ijọ awọn gẹgẹ bii: Idris, ati Nuh, ati Ibrahim, ati Musa, ati Isa, ati Hud, ati Solih, ati Shuaib, o si n bẹ ninu wọn ti Ọlọhun ko fun wa ni iro nipa orúkọ wọn, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe: Àti pé A kúkú ti rán àwọn Òjíṣẹ́ níṣẹ́ ṣíwájú rẹ. Àwọn tí A sọ ìtàn wọn fún ọ wà nínú wọn. Àwọn tí A ò sì sọ ìtàn wọn fún ọ wà nínú wọn. Àti pé kò tọ́ fún Òjíṣẹ́ kan láti mú àmì kan wá àfi pẹ̀lú ìyọ̀nda Allāhu. Nígbà tí àṣẹ Allāhu bá sì dé, A máa fi òdodo dájọ́. Àwọn òpùrọ́ sì máa ṣòfò dànù níbẹ̀ yẹn. [Ghafir: 78].



**5- Nini igbagbọ ninu ọjọ ikẹyin:** Oun ni ọjọ igbedide ti Ọlọhun maa gbe àwọn èèyàn dide nibẹ fun iṣiro ati ẹsan lori awọn iṣẹ wọn ti wọn ṣe ni aye, ti àwọn ènìyàn si maa pin si igun meji, awọn olugbagbọ a maa bẹ ninu alujanna ti wọn maa ṣe gbere nibẹ, awọn alaigbagbọ a maa bẹ ninu ina ti wọn maa ṣe gbere nibẹ, ẹni ti o ba jẹ olugbagbọ sugbọn o da awọn ẹṣẹ, ninu ki Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- ṣe aforijin fun un, tabi ki O fi iya jẹ ẹ fun ìgbà díẹ̀ lẹyin naa ki O mu u wọ alujanna.

**6- Nini igbagbọ ninu kadara eyi to daa nibẹ ati eyi to buru nibẹ:** Ki musulumi ni igbagbọ pe dajudaju Ọlọhun ni imọ nipa nǹkan ti o ti n bẹ ati ti yoo maa bẹ, ati pe dajudaju Ọlọhun kọ awọn kadara awọn ẹda, O si fẹ wọn nitori naa O mu u bẹ, nnkankan ko le ṣẹlẹ ni aye afi pẹlu imọ Rẹ, ati àkọsílẹ̀ Rẹ, ati fifẹ Rẹ ati dida Rẹ, to ba jẹ daadaa ni, a ṣe pe o jẹ ninu ikẹ Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- si i, ti o ba yatọ si iyẹn, a ṣe pe àdánwò ni o jẹ lati ọdọ Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga-, tabi ifiyajẹ, o lọ pẹlu ọgbọn Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- ati déédéé Rẹ, eyi to ṣe pe eniyan o le rọkirika ẹ pẹ̀lú imọ fun titobi rẹ ati pipe rẹ, ti ẹru ba ni igbagbọ ninu kadara, eyi to daa nibẹ ati eyi to buru nibẹ, ọkan rẹ a balẹ, ẹmi rẹ a sinmi, o si maa fa awọn alamọri rẹ le Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- lọ́wọ́; nitori pe dajudaju oun mọ pe gbogbo nnkan n bẹ lọwọ Ọlọhun nikan ṣoṣo; nnkan to ba fẹ ni yoo maa bẹ, nnkan ti ko ba fẹ ko nii bẹ





## Awọn origun Isilaamu

Awọn origun Isilaamu ni awọn ipilẹ rẹ ti wọn mọ ọn le lori, oun naa ni awọn origun maarun ti gbígbé e duro jẹ dandan fun Musulumi:

1- **Ijẹrii pe ko si ẹni kankan ti ijọsin ododo tọ si ayaafi Allāhu, ati pe dajudaju Muhammad ojiṣẹ Ọlọhun ni:** Oun naa ni ijẹrii kan ti wọn o wi i pẹlu ahọn, ti yio si ba ọkan mu, wipe dajudaju Allāhu ni Ẹni ti a maa n jọsin fun l'ododo ni Oun nikan ṣoṣo ti ko si si orogun fun Un, ati pe dajudaju Muhammad - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - oun ni ojiṣẹ ti o n jiṣẹ Ọlọhun

2- **Gbigbe Irun duro:** O wa jẹ dandan fun Musulumi ki o maa ki Irun maarun ni ojumọ (aarọ ati alẹ), Irun kan ni o ni iduro ati itẹkọkọ ati iforikanlẹ; lati gbe Ọlọhun ti ọla Rẹ ga tobi, o si tun ni awọn asiko ti wọn n fi orukọ rẹ pe e, oun naa ni: Irun Al-fajri, ati Irun Dhuri, ati Irun Asri, ati Irun Magrib, ati Irun Ishai, ati pe awọn Irun miran tun wa ti wọn kii ṣe ọranyan.

3- **Yiyọ Zakah:** Pẹlu ki Musulumi ti dukia n bẹ lọdọ rẹ o yọ odiwọn kekere kan pàtó ninu dukia rẹ, ki o si fi i fún awọn ti wọn lẹtọọ si i ninu awọn aláìní, ati awọn mẹkunnu, ati awọn to yatọ sí wọn ninu awọn ti a maa n fun ni Zakah.



**4- Aawẹ Ramadan:** Pẹlu ki Musulumi o ko ẹnu ro nibi jíjẹ, ati mimu, ati ibalopọ, ati nkan ti o jọ ọ ninu awọn nkan ti maa n tu aawẹ, lati ìgbà tí Al-fajri ba ti yọ titi ti oorun o fi wọ nínú oṣu Ramadan; lati jọsin fun Ọlọhun ti ọla Rẹ ga.

**5- Gbigbero ile Ọlọhun abeewọ:** Oun naa ni lilọ Musulumi si Makkah Alapọn-ọnle; lati lọ jọsin fun Ọlọhun ti ọla Rẹ ga pẹlu ṣíṣe awọn arisami iṣẹ hajj, koda ko jẹ ẹẹkan ninu ọjọ ori, fun ẹni ti o ba ni agbara iyẹn.



## Ijọsin ninu Isilaamu:

**Ijọsin:** Oun ni mimu Ọlọhun ti ọla Rẹ ga ni Ọ̀kan ṣoṣo, ati isunmọ Ọn pẹlu gbogbo nkan ti O ba nífẹ̀ẹ́ si ti o si tun yọnu si ninu awọn ọrọ ati iṣẹ ti o han ati èyí tí o pamọ.

- **Ninu awọn ọrọ ni:** Kika Kuraani, ati ṣiṣe adua, ati riranti Ọlọhun ti ọla Rẹ ga, ati kikọ imọ ti o ṣe anfaani, ati gbigba awọn ẹlomiran ni imọran, ati eyi ti o yatọ si i.
- **Ati pe ninu awọn iṣẹ ni:** Imọra ati Irun, ati Hajji, ati igbiyanju nibi gbigbọ awọn bukaata awọn eeyan, ati èyí tí o yatọ si i.
- **Ati pe Adh-Dhāhirah:** Oun ni awọn iṣẹ ti o han ti wọn o ri tabi gbọ ati eyi ti o jọ bẹẹ gẹ́gẹ́ bíi Irun, ati Hajji, ati kika Kuraani, ati pipepe lọ si ọdọ Ọlọhun, ati dida awọn mọlẹbi papọ.
- **Ati pe Al-Bātinah:** Oun ni awọn iṣẹ ti o maa n wa ninu ọkan; gẹ́gẹ́ bíi nini ifẹ Ọlọhun ti ọla Rẹ ga, ati nini agbiyele Rẹ ati pipaya Rẹ, ati irẹlẹ, ati igbarale Ọlọhun ti ọla Rẹ ga.




## Pataki ijọsin ninu Isilaamu:

Jijọsin fun Ọlọhun ti ọla Rẹ ga gan ni ohun ti Ọlọhun tori rẹ da awọn eeyan, Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: {Àti pé Èmi kò ṣẹ̀dá àlùjànnú àti ènìyàn bí kò ṣe pé kí wọ́n lè jọ́sìn fún Mi.} Suuratudh Dhāriyāt: 56.

Ati pe wọn ti ṣe ijọsin l’ofin fun awọn ọgbọn ti o tobi, ati awọn anfaani ti o pọ ti yio maa ṣẹlẹ̀ ninu ẹmi awọn eeyan ati isẹmi ayé wọn, ninu awọn ọla ijọsin si ni pe o maa n fọ awọn ẹmi mọ, o si maa ṣe e ni tonitoni, o si tun maa n gbe e ga lọ sí ibi tí o ga julọ ninu awọn ipele pipe ni ọmọniyan.

Ati pe ọmọniyan ni bukaata ti o tobi si ìjọsìn, gẹ́gẹ́ bí ara rẹ ṣe bukaata si ounjẹ ati omi, bákannáà ni ọkan rẹ ati ẹmi rẹ bukaata si idajukọ Ọlọhun pẹlu ijọsin; nitori naa ẹmi o le balẹ ayaafi pẹlu iranti Ọlọhun ati jijọsin fun Un, ọkan naa o si le layọ, bẹẹ inu ko le dun ayaafi pẹlu isunmọ Ọlọhun ti ọla Rẹ ga ati didara asopọ pẹlu Rẹ, ati pe awọn olujọsin tootọ awọn ni wọn ṣe oriire julọ ninu awọn eeyan, awọn si ni inu wọn dùn julọ; nitori naa ẹni ti o ba fẹ ìdùnnú, ki o yaa dunni mọ ẹnu ọna ijẹ ẹrusin fun Ọlọhun ni Oun nikan ṣoṣo.





## Gbigbooro ìjọsìn ninu Isilaamu:

Ijọsin ninu Isilaamu ko gbogbo iṣẹ rere ti Ọlọhun nífẹ̀ẹ́ si sinu, ati eyi ti a maa n fi ṣiṣe e rẹ sunmọ Ọlọhun ti O lágbára ti O si tun gbọnngbọn, o si ko sinu:

- Awọn arisami ti ijọsin: Gẹgẹ bii irun, ati zakah, ati aawẹ, ati hajj, ati kika Kuraani, ati adua, ati ìrántí Ọlọhun ti ọla Rẹ ga, ati eyi ti o yatọ si i.
- Ati ibalopọ daadaa: Gẹgẹ bii ṣiṣe daadaa si obi mejeeji, ati dida ebi papọ, ati ibalopọ daadaa pẹlu iyawo ati awọn ọmọ, ati tita rira to daa, ati ṣiṣe awọn iṣẹ daradara, ati ṣiṣe daadaa si awọn ara àdúgbò, ati riran awọn mẹkunnu lọwọ, ati ṣiṣe daadaa si awọn ẹranko, ati nkan ti o yatọ si iyẹn.
- Ati pe o ko awọn iwa daadaa sinu; bii ọrọ ododo, ati dídá àgbàfipamọ́ pada, ati pipe adehun, ati irẹrin-in musẹ, ati ọrọ daadaa, ati itiju, ati eyi ti o yatọ si iyẹn ninu awọn iwa.

Nitori naa Musulumi o maa jọsin fun Ọlọhun ni gbogbo awọn ìṣesí rẹ; yio maa jọsin fun Ọlọhun ninu Mọṣalasi, ati ninu ile, ati nibi iṣẹ, ati ni gbogbo aaye, gbogbo isẹmi rẹ ti Ọlọhun ti ọla Rẹ ga ni, Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Sọ pé: Dájúdájú ìrun mi, ẹran (pípa) mi, ìṣẹ̀mí ayé mi àti ikú mi ń jẹ́ ti Allāhu, Olúwa gbogbo ẹ̀dá. [Al-An'am: 162].


1
39
STREET
ROAD
طريق
RING ROAD



## Ipilẹ kẹta

# Ta ni Anabi rẹ ؟

## Anabi mi ni Muhammad - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a.

“Anabi wa ni: Muhammad ọmọ Abdulahi ọmọ Abdul-Muttolib ọmọ Haṣim, ti iran rẹ ṣẹri pada si ọdọ Anabi Ọlọhun Ismaheel ọmọ Anabi Ọlọhun Ibrahim- ki eyi to lọla julọ ninu ikẹ Ọlọhun ati ọla maa ba wọn ati Anabi wa-

Ọlọhun gbe e dide ni Mẹka alapọn-ọnle ti ọjọ-ori rẹ jẹ ọmọ ogoji ọdun, ti Ọlọhun si sọ Kuraani kalẹ fun un, o si pe awọn eniyan si imu Ọlọhun lọkan ṣoṣo ati si ẹsin Isilaamu, awọn ijọ rẹ si fi suta kan an ni eyi to le koko julọ ninu suta, ti wọn si fi iya jẹ awọn saabe rẹ ti wọn si pa aimọye ninu wọn, lẹyin naa o ṣe hijira lọ si ìlú Yathrib (lẹyin naa orúkọ rẹ di Madina ti Anabi) lẹyin ọdun mẹtala, nibẹ ni o ti gbe ijọba Isilaamu duro, ti o si fi awujọ ti Isilaamu lélẹ̀, o ṣi wa nibẹ fun ọdun mẹ́wàá ti o n tọ́ni sọna ti o n pepe ti o si n kọni lẹkọọ, ti o si



tẹ siwaju lori iyẹn titi ti ofin sharia fi pe, ti Isilaamu naa si pe pẹlu iyẹn ti ẹsin si di odidi, ni ọrọ Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- wa sọ kalẹ pe: {Mo parí ẹ̀sìn yín fun yín lónìí. Mo sì ṣe àṣepé ìdẹ̀ra Mi fun yín. Mo sì yọ́nú sí ’Islām ní ẹ̀sìn fun yín}. (Al’Maa’idah 3) lẹyin naa ni Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ku lẹyin igba ti oju rẹ ti tutu pẹlu riri awọn eniyan ti wọn wọ inu ẹsin Ọlọhun ni ti ifẹ ati ifinnufindọ, gẹgẹ bi Ọlọhun- Ọba ti O gbọnngbọn ti O ga- ṣe sọ pe: {Nígbà tí àrànṣe Allāhu (lórí ọ̀tá ẹ̀sìn) àti ṣíṣí ìlú (Mọ́kkah) bá ṣẹlẹ̀ (1) tí o sì rí àwọn ènìyàn tí wọ́n wọnú ẹ̀sìn Allāhu níjọníjọ (2) nítorí náà, ṣàfọ̀mọ́ pẹ̀lú ìdúpẹ́ fún Olúwa rẹ. Kí o sì tọrọ àforíjìn lọ́dọ̀ Rẹ̀. Dájúdájú Ó ń jẹ́ Olùgba-ìronúpìwàdà}. [An-Nasr: 1-3].

## Anabi ikẹ:

Anabi wa Muhammad- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ni Anabi ikẹ, ikẹ ko fi i silẹ ni gbogbo aye rẹ, ati nibi gbogbo awọn ipele igbesi aye rẹ ati awọn iṣesi rẹ, Ọlọhun -ti ọla Rẹ ga- sọ pe: A kò sì fi iṣẹ́ ìmísí rán ọ bí kò ṣe pé kí o lè jẹ́ ìkẹ́ fún gbogbo ẹ̀dá. Suratul Anbiyaah: 107. “Ninu ikẹ rẹ- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ni pe o jẹ olojukokoro gan-an lori titọ awọn eniyan sọna, ati mimu wọn jade kuro ninu okunkun aigbagbọ ati aimọkan ati anu, si inu imọlẹ igbagbọ ati imọ ati imọna, igba ti o ri i pe awọn ijọ rẹ ko gbagbọ, o fẹẹ le pa ara rẹ run ni ti ibanujẹ lori aini igbagbọ wọn, Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe: Nítorí náà, nítorí kí ni o ṣe máa fi ìbànújẹ́ para rẹ lórí ìgbésẹ̀ wọn pé wọn kò gba ọ̀rọ̀ (al-Ḳur’ān) yìí gbọ́. [Al-Kahf: 6]. Bákan náà awọn itumọ ikẹ rẹ n hàn nibi



ojúkòkòrò rẹ lori awọn olugbagbọ ati aanu rẹ pẹlu wọn, Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe: Dájúdájú Òjíṣẹ́ kan ti wá ba yín láti ààrin yín. Ohun tí ó máa kó ìnira ba yín lágbára lára rẹ̀. Ó ń ṣe àkólékàn (oore ọ̀run) fun yín; aláàánú àti oníkẹ̀ẹ́ ni fún àwọn oní gbàgbọ́ òdodo. Sūratut Taobah: 128. "Ninu ojúkòkòrò rẹ lori mímú ẹsin rọrùn ati aila nnkan to le ko inira ba awọn ijọ rẹ bọ wọn lọrun, ati nnkan ti wọn ko ni ikapa lati ṣe, Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe: "Ẹ ṣe idẹkun ki ẹ ma ṣe ni awọn eniyan lara, ẹ fúnni ni iro idunnu, ẹ ma ṣe le awọn eniyan sa". Bukhari ati Muslim ni wọn gba a wa.


Ẹmi Ojiṣẹ alapọn-ọnle kun fun ikẹ, o jẹ ẹni ti o maa n kẹ àwọn obìnrin julọ ninu awọn eniyan, ati awọn ọmọ, ọkan ninu awọn saabe rẹ tii ṣe Anas ọmọ Maalik- ki Ọlọhun yọnu si i- sọ pe: Mi ko ri ẹni kankan to jẹ ẹni ti o maa n kẹ awọn ẹbi julọ ti o to Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- Muslim ni o gba a wa.

"Ikẹ rẹ- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ko mọ lórí awọn eniyan, bi ko ṣe pe o de ọdọ awọn ẹranko, o pepe si iṣe dáadáa si wọn, o si ṣe ikilọ kuro nibi fifi suta kan wọn, o si ṣe alaye fun awọn saabe rẹ pe arabinrin oniṣina kan fun aja kan ni omi mu, ti Ọlọhun si ṣe aforijin fun un, o si mu u wọ alujanna, arabinrin kan si wọ inu ina; nitori pe o de olongbo kan mọlẹ, ti ko si fun un ni oúnjẹ titi ti o fi ku.

## Iranṣẹ rẹ to kari gbogbo awọn eniyan:

Awọn Anabi ati awọn Ojiṣẹ ti wọn ti ṣaaju- ki ikẹ ati ọla maa ba wọn- jẹ awọn ti wọn ran si awọn ijọ wọn nìkan, ṣùgbọ́n Anabi Muhammad- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- iranṣẹ rẹ kari gbogbo awọn eniyan ni gbogbo igba ati aaye.

Ọlọhun- ti ọla Rẹ ga- sọ pe: {A ò rán ọ nísẹ́ àfi sí gbogbo ènìyàn pátápátá; (o jẹ́) oníròó-ìdùnnú àti olùkìlọ̀}. Suratu Sabai: 28 Allah ti ọla Rẹ ga julọ tun sọ pe: {Sọ pé: Ẹ̀yin ènìyàn, dájúdájú èmi ni Òjíṣẹ́ Allāhu sí gbogbo yín pátápátá} Suratul A'raf: 158 Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe: Wọ́n maa n gbe Anabi dide si ijọ rẹ nìkan, wọn si gbe mi dide si awọn eniyan lapapọ. Bukhari ni o gba a wa. Itẹle rẹ ati gbigba nnkan ti o mú wá lododo, ati wiwọ inu ẹsin rẹ jẹ dandan fun gbogbo eniyan lati igba igbedide rẹ- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ati ni asiko yii ati titi di ọjọ igbedide, ati pe dajudaju Ọlọhun ti fi opin si awọn iranṣẹ ti sanmọ pẹlu rẹ, O si ṣe itẹle rẹ ni dandan; ẹnikẹni ti o ba tẹle e maa ṣe oriire ni aye, o si maa wọ alujanna ni ọjọ ikẹyin, ẹnikẹni ti o ba yapa rẹ maa ṣe oriburuku ni aye, o si maa wọ ina ni ọjọ ikẹyin, Ọba- ti ọla Rẹ ga- sọ pe: {ẹnikẹ́ni tí ó bá tẹ̀lé ìmọ̀nà Mi, kò níí ṣìnà, kò sì níí dààmú (123). " Ẹnikẹ́ni tí ó bá sì ṣẹ́rí kúrò níbi ìrántí Mi, dájúdájú ìṣẹ̀mí ìnira máa wà fún un nílé ayé. A sì máa gbé e dìde ní afọ́jú ní Ọjọ́ Àjíǹde." [Taha: 123, 124].





## Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ninu ile rẹ, ati pẹlu awọn ara ile rẹ:

Ile eniyan ni aaye kan ti o maa ṣe afihan dídára iwa rẹ, ati pipe ẹkọ rẹ, ati dídára ibalopọ rẹ, igba ti eniyan ba n wa pẹlu iyawo rẹ tabi awọn ọmọ rẹ tabi ọmọ-ọdọ rẹ, dajudaju yio maa huwa bi Ọlọhun ṣe da a laini fi agidi ṣe e.

Ẹnikẹni ti o ba n woye si iṣesi Ojiṣẹ ijọ Isilaamu ati adarí rẹ ati olukọ rẹ- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ni ile rẹ, yoo ri pe o fi eyi to daa julọ ninu awọn àpẹrẹ lélẹ̀ fun nnkan to tọ ki ọkùnrin abiyi maa wa lori rẹ ni ile rẹ ati pẹlu ìyàwó rẹ ati awọn ọmọ rẹ.

Wọn sọ fun A'isha iyawo Anabi- ki Ọlọhun yọnu si i- pe: Ki ni nnkan ti Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- maa n ṣe ni ile? O sọ pe: "O jẹ ẹni ti o maa n ṣe ídímọ́ àwọn ìyàwó rẹ- o n tumọ si riran awọn ara ile rẹ lọwọ- ti asiko irun ba ti to, o ma lọ kirun" Muslim ni o gba a wa. Anabi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- jẹ ẹni ti o daa julọ ninu awọn eniyan si awọn ara ile rẹ ati awọn iyawo rẹ, o maa n ti aworan to daa ṣíwájú nibi dídára ibagbepọ, ati rirọ ni ẹ̀gbẹ́, ati mimọ awọn nnkan ti o n wu ẹmi iyawo rẹ, o si maa n lo àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ lati dun ìyàwó rẹ nínú, A'isha- k Ọlọhun yọnu si i- n sọ pe: Dajudaju mo ti ri Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ni ọjọ kan nibi ilẹkun yara mi ti awọn ọmọ ilu Abasha n ṣere ninu mọsalasi, ti Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- si n bo mi pẹlu aṣọ rẹ, ti mo si n wo eré wọn ti wọn n ṣe". Bukhari ati Muslim ni won gba a wa.



Ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- nífẹ̀ẹ́ àwọn ọmọbìnrin rẹ, o si maa n pọn wọn le; ti ọmọ rẹ Fatimah ba wọlé tọ ọ, o maa dìde lọ ba a, o si maa fi ẹnu ko o ni ẹẹkẹ, o si maa ni ki o jókòó si ààyè rẹ, o si tun maa n ṣe abẹwo àwọn ọmọbìnrin rẹ lati mọ iṣesi wọn

Ninu àsọtẹ́lẹ̀ rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- fun ìjọ rẹ ni ọ̀rọ̀ ti o sọ pé: “Ẹ maa ṣe dáadáa si awọn obìnrin” Bukhari ati Muslim ni won gba a wa.



## Ninu awọn ìwà Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ni pe:

Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ni iwa rẹ dáa ju ninu awọn èèyàn, oun si ni o ni ẹkọ ju, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga royin rẹ pe: Dájúdájú ìwọ sì wà lórí ìwà àpọ́nlé. [Al-Qalam: 4] O pe ni ìwà debi pe ko si ẹlomiran ti o to o, ti wọn si ṣọ ọ kuro nibi gbogbo iwa àbùkù, Alukuraani ṣi ni iwa rẹ, oun ni o fi n gba ẹkọ, ti o si fi n kọ àwọn èèyàn, ninu awọn iwa rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ni pe:

- Oun ni o ni sùúrù ju ninu awọn èèyàn ti o si ni déédéé ju nínú wọn, ti o si mọ ju, ti o tun maa n tọrẹ ju ninu wọn.
- O tun jẹ ẹni tí ó ni ìtìjú ju ninu awọn eeyan.
- O jẹ onitẹriba ti o si maa n dáhùn ipepe ẹnikẹ́ni ti o ba pe e, o si maa n gba ẹbun kódà ki o kéré, o si maa n ṣẹsan lori rẹ
- O maa n ṣe abẹwo àwọn aláìsàn, o si maa n wa nibi ètò ìsìnkú, o si maa n jókòó ti àwọn talika, o si maa n ba àwọn mẹkunnu jẹun papọ, o si maa n ṣe apọnle àwọn ọlọla ati awọn oníwà rere, o si maa n fa ọkàn àwọn ẹni iyì mọ́ra
- Ẹni kankan ko nii waa ba a afi ki o ba a gbọ bukaata rẹ, kii ṣe oníwà líle, ko si buru, kii fi aburu ṣẹsan aburu, ṣùgbọ́n o maa n ṣe amojukuro, ayafi ti wọn ba fa ọgbà Ọlọhun ya, ìgbà naa ni o maa binu tori ti Ọlọhun, kii ṣe tori ara rẹ̀
- Ninu iwa rẹ ni ki o kọkọ salamọ si ẹni ti o ba pade rẹ, ti o ba pade ikan ninu awọn saabe rẹ, o maa kọ́kọ́ bọ ọ lọ́wọ́



- O maa n kọju si ẹni ti o ba jókòó ti i, o si maa tẹti si i, o si maa ba a sọ̀rọ̀, o si maa tọ ọ sọ́nà
- Oun ni o ni aanu ju ninu awọn èèyàn, ti o si lóore ju ti o si ṣe anfaani ju fun àwọn èèyàn
- O maa n ṣe awada ti ko ni irọ nínú, o maa n rẹẹrin musẹ lọpọlọpọ, o si tun maa n rẹẹrin ti kii ṣe ẹrin keekee, o maa n ba àwọn ìyàwó rẹ ṣe ìdíje, o si maa n ṣe dáadáa si wọn
- Ohun ti o ba wa nílẹ̀ ni o maa n jẹ, kii sii da ohun ti o ba wa nílẹ̀ pada, kii bu oúnjẹ rárá, ti o ba ri dabinu o maa jẹ ẹ, ti o ba ri ẹran o maa jẹ ẹ, ti o ba ri búrẹ́dì o maa jẹ ẹ, ti o ba ri ohun ti o dun tabi oyin o maa jẹ ẹ, ti o ba ri wàrà lai si búrẹ́dì o maa tẹ ẹ lọrun, ti o ba ri bàrà olómi tabi dabinu tútù o maa jẹ ẹ
- Ohun ti o ba ri ni o maa n wọ̀, ìgbà mii o le wọ aṣọ idabora, ìgbà mii o le wọ aṣọ gbagẹrẹ, eyi ti o ba ri ninu aṣọ ti o lẹtọọ ni o maa wọ̀
- O maa n gun ohun ti o ba rọrùn fun un, ìgbà mii ẹṣin, igba mii ràkúnmí, igba mii ìbaaka, ìgbà mii kẹ́tẹ́kẹ́tẹ́, tabi ki o fi ẹsẹ rin
- Àkókò rẹ kii lọ lai ṣe iṣẹ́ kan fun Ọlọhun, tabi ohun ti o gbọdọ̀ ṣe bii àtúnṣe ẹmi rẹ ati ti àwọn ará ilé rẹ

Ati ohun ti o yatọ si ìyẹn nínú àwọn iwa rere ati ibalopọ dáadáa, ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a.





# Ọrọ ipari

Ẹsin ńlá ni Isilaamu, o maa fun Musulumi- ti o ba n ṣe àmúlò àwọn ẹkọ rẹ- ni ìsinmi ati iṣẹmi ti o dara, ati iṣesi ti o daa ni ayé, ati idẹra gbere, ati ìdùnnú láéláé ni ọjọ́ ìkẹyìn. Gẹ́gẹ́ bẹẹ naa ni o ṣe maa fun àwùjọ Islam ti n ṣe àmúlò àwọn ẹkọ rẹ ni agbega, ati itẹsiwaju, ati ìdàgbàsókè, ati isọkan àwùjọ, ati ifọkanbalẹ ati aabo

A ki ọ ku oriire, ìwọ ti o ba gba Islam, fun idẹra nla yii, ti o wa kọ nipa adisọkan rẹ, ati ofin rẹ, ati awọn ẹkọ rẹ, ati awọn ìdájọ́ rẹ, ati awọn iwa rẹ ati ẹ̀kọ́ rẹ, ti o si dirọ mọ ìyẹn ninu ẹ̀mí rẹ, ti o si ṣe àmúlò rẹ ninu gbogbo iṣẹmi rẹ bi o ṣe lágbára mọ, onítọ̀hún maa ri oripa Islam lara rẹ, ati bi o ṣe máa sọ ọ di eeyan rere, inu rẹ maa dun, àwọn ti wọn yika rẹ naa si maa dunnu; bii àwọn obi, ìyàwó, àwọn ọmọ, àwọn ẹbi, àwọn ará àdúgbò, ati awọn ọrẹ, ati gbogbo ẹni ti ba n ba Musulumi yii lo papọ, ẹni tí Ọlọhun pọnle pẹ̀lú wiwọ inu ẹsin Rẹ, ati rírìn ni ojú ọ̀nà ti o maa mu u de ibẹ̀.

Tira kékeré yii ni ibẹrẹ ọ̀nà rẹ lati kọ àwọn ìdájọ́ ẹsin rẹ, lẹ́yìn naa o di dandan fun ẹ lati gbìyànjú lati lekun ni imọ ti o ṣe anfaani ati iṣẹ rere, ati fifọ ẹmi rẹ mọ, ati titun ọkàn rẹ ṣe. Gbogbo igba ti ìmọ̀ rẹ nipa Islam ba ṣe n lekun ati àmúlò ohun ti o kọ, naa ni isunmọ rẹ si Ọlọhun ṣe maa lekun, gbaju mọ Kuraani Alapọn-ọnle pẹ̀lú kikọ ọ, ati kika a, ati rironu jinlẹ nipa àwọn aaya rẹ. Ka nipa itan ìgbésí ayé Anọbi Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ati sunna rẹ; oun ni awokọṣe rẹ ni ayé yii, oun nikan si ni Ọlọhun pa ọ láṣẹ lati gba gbogbo ohun ti o mu wa, ṣùgbọ́n ẹda abara ti o ba ti yatọ si i, bi ipo rẹ ba ti wù kí ó tó, a maa gba ọrọ wọn ti o ba ba Kuraani ati Sunna mu, a si maa da ohun ti o ba yapa wọn pada, ki o ṣi sọra fun iyan jija nínú ẹsin ati iyapa, ati ifanfa pẹ̀lú àwọn ọmọ-ìyá rẹ Musulumi.

A n bẹ Ọlọhun fun wa ati fun ẹ, kongẹ ati ifẹsẹrinlẹ ninu ẹsin yii tító tí a fi maa pade rẹ ti O maa yọnu si wa, ọpẹ ni fun Ọlọhun Oluwa àwọn ẹda, ki ikẹ ati ọla maa ba Anọbi wa Muhammad, ati awọn ara ilé rẹ, ati awọn saabe rẹ lapapọ, ati awọn ti wọn ba tẹle e titi di ọjọ ẹsan.

مركز أصول
OsoulCenter
www.osoulcenter.com

Chat in your language

Fi ọ̀rọ̀ wérọ́ nipa Islam pẹ̀lú awọn ede pupọ

OSOUL STORE

Láti gba ẹ̀dà tira naa sílẹ̀ ati awọn tira míràn pẹ̀lú èdè pupọ

GUIDE TO ISLAM

Láti mọ̀ síi nípa Isilaamu

**Ẹni ti o ba gba ẹsin Isilaamu ti o si dirọ mọ ọn,** dajudaju o n rin ni oju-ọna imọlẹ ati imọna; ọna taara ti o fi oju han ti o maa muni de ọdọ Ọlọhun ti O da eniyan ti o si mu u bẹ ni aye yii.

**Ẹsin Isilaamu wa pẹlu** dídára iṣesi eniyan ati ifọkanbalẹ rẹ ati ìdùnnú rẹ ni isẹmi aye rẹ, ati ìdùnnú rẹ bákannáà ati ere rẹ ni isẹmi ọjọ́ ikẹyin rẹ lẹyin to ba ku, nigba ti Ọlọhun -ti ọla Rẹ ga- ba mu u wọ alujanna ti o maa gbadun pẹlu nnkan to wa nibẹ ninu idẹra gbere.

**O wa jẹ dandan** fun gbogbo eniyan lati ṣe ìwádìí nipa ẹsin ododo tii ṣe Isilaamu, ki o si mọ ọn, ki o si wọnu ẹ ni olugbagbọ si i, ki o si maa tẹle awọn ẹkọ ẹ ati awọn idajọ ẹ, ki ọwọ ẹ le tẹ daadaa aye ati ọrun.


osoulcenter

www.osoulcenter.com

Láti gba ẹ̀dà tira naa sílẹ̀ ati awọn tira míràn pẹ̀lú èdè pupọ

OSOUL STORE

osoulstore.com